# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 945 LAG S SATURDAY OCTOBER 31 — NOVEMBER 6 1964 KỌBỌ MEJI (2D


# Rogbodiyan Besile Larin Egbe Olope ati Alakuko Ni Ibadan

IBADAN— A ti dibo ku si dẹdẹrogbod yau bẹsilẹ larin awọn ẹgb oṣelu meji ti nwọn ṣẹṣẹ parapọ ti nwọn npe oru ọ w n ni UPGA awọn ẹgbẹ Alakukọ ni Ibadan.

Nkan ti a gbọ w pe o fa ọrọ rogbodiyan na ni ti awọn aṣoju ti nwọn fẹ yan sode wipe ti nwọn dibo fun. Awọn kan ni awọn ọmọ ẹgbe Ọlọpẹ ni awọn ni awọn lẹiọ lati yan gbogbo aṣoju mẹje ti Ibadan sita: awọu ọmọ ẹgbẹ Alakukọ paapa fẹ ko gbogbo ijo o Ibadan ni a otan. A gbọ w pe nwọn fẹ ko ijoko ju eyiti nwọn fun awọn ẹgbẹ wọn lọ.

Alhajui Busari Obiṣesa ọkan ninu awọn aṣiwa u ọmọ ẹgbe awọn ti ṣe adehun si lori pipin ijoko meje ti nwọn y n fun awọn ara Ibadan lati dibo fun.

Alhaji D.S. Adegbənro paapa se alaye wipe ijoko mẹta, ọkan ni agbegbe Ibarapa, meji ni arin Ibadan ni ijoko aṣoju ti nwọ van fun egbẹ Ọlọpẹ, nwọn ni ki awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ko ijoko mẹrin yoku.

Ọgbeni Adeoye Adisa alaga awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ni awọn ko fi gbakan ṣe adehun lori awọn ijoko idibo Ibadan pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ. A gbọ wipe awọn gbalagba ti nwọn wa ninu awọn ẹgbẹ mejeji si mba wọn yauju ọrọ rogbodiyau na lọwọ.

# Egba Se Bebe L'Ebute—Metta

EBUTE METTA– Awọn iran onigbagbọ ọ ọ onigbagbọ Ẹgba ti awọn baba wọn sa kuro ni ilu Abẹokuta nigbati OTẸ IFỌLE awọn Onigbagbọ ni iwọn nkan bi ọdun mẹtadinlogun ṣe bẹbe ni AGỌ ẸGBA laipẹyi nigbati gbogbo wọn lọ si Ṣọsi St.Jude lati lọ ṣe isin iranti ọdun na.

Nitorio ọdun 'buruku ni ọdun 'na jẹ fun awọn ọmọ Ẹgba ti nwọn ṣẹṣẹ di O igbagbọ ni ilu Abẹoku a nigbana nitoripe awọn ara wọn awọn aborisa ti nwọn wa ni ilu nigbana ṣe inunibini si wọn pupọ. Nwọn fọ ile wọn pẹlu Ṣọsi ti nwọn npejọ ṣe isin

Eleyi ni o mu ki ọpọlọpọ awọn onigbagbọ igbana sa asala wa si Eko pẹlu awọn Oyinbo ojiṣẹ Ọlorun ti nwọn wa ni Abẹokuta Ilu Abẹokuta ni awọn Oyinbo ajihinrere Ijọ C. M. S. kọ fi ṣe ibuj ko pataki tabi olu ilu ilẹ wọn ni gbara ti nwọ kọkọ de si ilẹ Nigera.

( Wo yoku loju ewe keji )

# Omo Olomo Ko Se Gba Se Omo

Ki a to ma ba itan wa yi lọ, o yẹ ki n gbadun meji yi. Ki Ọlọrun ma ṣe jẹki a fi ọmọ ọlọmọ ṣe ọmọ Li Ọloruu ma ṣe jẹki ay alaya ṣe aya. Amin.

Nibiti a ba itan wa y de n wipe ọkan ninu ọṣọ rẹ ni awọn oṣu tabi aṣo mẹta ti o da si ori rẹ. Ikan mbẹ ni iwaju nkan larin ati ikan ni ipakọ rẹ, a ma ṣe iroju wọn gẹgẹb obinrin ti o fi j ti o ma nroju irun ori rẹ.

( Wo yoku loju ewe kẹfa )

# E Ka ro

Arikogbon Ede Owe Ni Ede Yoruba Ati Oyinbo ni oju ewe kefa.

# ELETI - OFE

(A NIJU WON KO SE WI LIJO)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAM

28, Kosoko Street; Lagos, "ELETI-OFE" Lagos
P. O. Box 467, Phone 23370

VOL. XIV NO 945 SATURDAY Oct 31 — Nov. 6 1964.


## ORO OLOTU:

# Iwa Aimore Ni Yi!

Lati bi ọsẹ meji ti awọn asiwaju ẹgbẹ oṣelu ilu Rọsia ti nwọn npe ni Komunisi (Communist Party) ti yọ Ọgbẹni Kurusofu (Nikita Khruschov) ni oye asiwaju wọn ni ogunlọgọ ọpọlọpọ awọn ọmọ ẹgbẹ na ti nwọn ni ẹka kakiri agbaiye ti bẹrẹsi fi ẹnu atẹ 'u ọna ti nwọn gba yọ Ọgbẹni Kurusofu na. Nwọn ni iwa awọn asiwaju ẹgbẹ oṣelu na dabi IWA ALAIMORE.

Nwọn ni bi o ti wu ki ẹṣẹ asiwaju awọn na buru to o yẹ ki nwọn gbe ẹjọ rẹ wa si awujọ gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ, ko yẹki nwọn doju tii larin gbogbo awọn oṣelu aiye bayi.

Awọn ọmọ ẹgbẹ Komunisi ni titi di oni awọn ko tilẹ ti mọ ibiti awọn oṣelu ilu Rọsia gbe ju Ọgbẹni Kurusofu si debi ti awọn yio fi le gbọ tẹnu rẹ nitoripe agbalagba ti o ba gbọ tẹnu ẹnikan dajọ ika-alagba ni iru iwa bẹ kosi ba eto ijọba iere mu.

Ẹnyin ọkawe wa, kosi ibiti ese kosi, Ọrọ awọn oṣelu Rosia (Russia) pẹlu asiwaju eto Ijọba wọn na dabi ọrọ awọn baba wa kan ti nwọn ni "ODE LAA S'AGBA ILE KAN BI IBO" Nitotọ O R E N'IWỌN. Bi ko ba ye yin, awọn Yoruba ni niwọn ni a nṣe ore mọ.

Ki a wa sọ ọrọ na ki o ye ẹnyin ọkawe iwe iro hin Eleti-Ofẹ Boya ẹ le bere wipe iru ore wo ni Ọgbẹni Kurusofu se fun awọn ara ilu Rọṣia ti awọn oṣelu ilu miran ẹlẹgbẹ Komunisi fi fe pe wọn ni alaimore ni didutoye ti nwọn du u loye asiwaju olotu eto Ijọba ilu Roṣia na.

Ẹgbẹ agbaiye Komunisi ni Ọgbẹni Kurọsofu ṣe bebẹ fun alafia awọn araiye Nwọn ni asiko tirẹ ni awon se ero ti awọn fi nwọ oju sanmọ lọ ti awọn nyika aiye: nwon ni asiko tire ni ilu Rọṣia di alagbara pẹlu etu bọmbu oloro eyiti awọn ijọba alagbara miran fi mbẹru awọn lọjọ oni. Nwọn ni kosi akuṣẹ ni ilu Rọṣia lọjọ oni.

Nitotọ kosi ẹniti o le tẹ araiye lọrun iwa alaimore pọ ninu aiye ti a wa yi bẹna ni o si ti wa nigbati aiye ti da aiye. Sugbọn paṣan ti a fi na iyale ni ọrọ na, pasan na mbe laja ti a fi pamọ lati tun fi na iyawo.

Ọrọ re o, ẹnyin ara wa, ẹniti o ba leti lati fi gbọ ki o gbọ. Ọgbẹni Kurusọfu ti se iwon ti o le ṣe, iyoku di ọwọ awọn ara ilu Rọṣia l'ọkunrin ati l'obinrin.

# Egba Se Bebe L'Ebute – Metta

(O bere loju ewe kinni)

ỌRỌ ote ilofe yi ni o mu ki awon Oyinbo ojiṣẹ Ọlọrun C. M. S. ko gbogbo ile iṣe ijoko wọn kuro ni Abeokuta ti awọn fi wa fi Ekọ se olu ijoko wọn.

Gomina Glover (GOLOBA) ni Gomina ti o wa l'Eko nigbati awọn onigbagbọ Ẹgba sa kuro nilu wa sasamo si Eko. Nigbati awọn Ẹgba gun si Eko kosi iẹ to fun wọn lati fiko ile isin ati ile ibugbe eleyi ni o mu ki Gomina Glover (KOLOBA) wa ibudo kan fun wọn ni Ebute-Metta niru ile awọn Oloye Ọlọtọ Adugbo awọn Egba ti nwon npe ni AGỌ ẸGBA di ọjọ oni ni Ebute-Metta

Alufa Ẹn-ọwọ Dokita J. O. Lucas ni ẹniti o ṣe iwasu ninu isin iranti ọdun ifọ'e na ti nwọn ṣe laipẹyi ninu Ṣọsi St Jude, ti o jẹ Ṣọsi akọkọ ti awọn Ẹgba kọ si Ago wọn na, gbogbo ẹṣẹ awọn ọmọ Ẹgba lọkunrin ati lobinrin ni nwọn pesibẹ ṣọṣọ pẹlu Oloye Ogundimu Ọlọtọ ti Ọtọ ni Eko.

Lehin isin na nwọn lọ si ile olori wọn Alagba T. M. Ṣogunle ni opopo Abẹokuta nibiti nwọn gbe fi nkan jijẹ ati awọn nkan mimu ṣe awọn eni ni alejo

# Awon Arufin Sa Kuro Ni Itimole L'Aba

ABA — Awọn arufin mẹdogun kan ni a gbọ wipe nwọn sa kuro ni itimọle ni Ọjọ Bọ to koja nigbati ija nla kan be sile larin awon ara ile'olo kan pelu awọn oṣiṣẹ Kansulu ti ilu Aba pelu awọn orinṣẹ kotu ibilẹ lapa keji ni ilu kan ti nwọn npe ni Obehie nitosi Aba.

Irohin kan to jade ni Aba ni ọjọ na nfi ye ni pe l'ẹhinmọ awọn ẹdaran to wa ninu kotu ibilẹ na ni nwọn fọ tutu tobẹ ti awọn arufin mẹdogun fi fẹsẹ fẹ nwọn si salọ bamubamu.

( Wo yo'u loju ewe kẹfa )

# Eleti - Ofe Daraba

# Ijoba Fi Wakati Kan Ise Awon Osise Eko

EKO— Aṣẹ de lati ọwọ ijọba apapọ pe wipe gbogbo awọn ile iṣẹ ijọba ti igboro Eko nilati ma ṣe osoji wakati lọsẹ-lọsẹ eyiti yio bẹrẹ lati ọjọ kini oṣu kewa ọdun yi.

Ni igboro Eko wakati iṣẹ yio lọ bayi lati Ọjọ Aje titi de Ọjọ Ẹti (Mondays-Fridays) agogo n ẹjọ owurọ titi di agogo mẹta ọsan Ọjọ Abamẹta nikanṣoṣo (Saturdays) agogo mẹjọ owurọ titi di agogo kan ọsan.

nwọn nfi ye ni pe ki gbogbo awon oṣiṣẹ ijọba ti nwọn ba wa ni ipinle ilu to ku ma ṣe iṣẹ wọn lọ gẹgẹbi iṣe wakati ti nwọn nto nibẹ.

Nigbati i ede yi ti i'e iṣẹ awọn alakoso isẹ didasile ati awọn eto mpa iṣẹ jade ni Ọjọ B to koja,

Agbo wipe awọn alakoso iṣe ijọba ti Ipinle Ila ati Iwo Orun ni Enugu ati Ibadan papa ti yi asiko iṣẹ awọn oṣiṣẹ wọn da si agogo mẹta ọsan.

# Enikan B'Obinrin Tage D'ogba Ewon

IFỌ — Ọkunrin kan ti orukọ rẹ nje Momo Iroru ẹni ọdun marun din logoji ni a gbọ pe o ba ọmọ binrin ẹni ọdun mẹjila kan lo pọ tipatipa ti adajọ agba Ọgbẹni O. Akinkugbe si sọ sẹwọn ọdun marun ni kotu nla ni Abẹokuta on paapa ni on gba pe on jẹbi ẹsun na.

Gẹgẹbi ọrọ ti awọn ọlọpa sọ ni iwaju adajọ nwọn ni ni ọjọ kẹdọgbọn osu keji ọdun yi ni ilu Ẹgba-Ifo, ọdaran yi ba ọmọbinrin na o ni Aminatu to nta ẹpa lo pọ lẹhin ti o ti fi ọgbọn t o wọ inu yara rẹ.

Nwọn ni lẹhin ti o ti ra ẹpa oni kọbọ lọwọ rẹ tan o ni ki obinrin na wọle wa gba owo ẹpa ti on ra nigbati nwọn de inu yara tan, Momo da dubulẹ tipatipa lẹhin ti o ti ga ẹsẹ re mejeji tan o ba ba lo pọ ẹje ba nṣan jade nidi ọmọ binrin na.

Awọn ọlọpa tun se ala ye pe ki ọmọ ẹlẹpa yi ma ba fi igbe tu aṣiri sta Momo ba oku ag ie alasomowọ kan ati sisi (6!) le ọmọ lọwọ gẹgẹbi ẹbun itunini ati mu ọmọ ki o to fi silẹ.

Nigbati Aminatu n dide, iya rẹ ṣe akiyesi ami ẹjẹ lara aṣọ rẹ lẹhin ibere bi ẹjẹ ṣe de ara aṣọ rẹ, Aminatu ba ṣe alaye bi gbogbo ọkan yi se ṣẹlẹ fun iya rẹ, laiṣe mẹji iya Aminatu ba lọ ke pe awọn ọlọpa.


## E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin Eleti — Ofe

ti o kun fun irohin aladun losose


# E ka oro oga olopa

**Ninu esun ponun mewa**

**( loju ewe kerin )**

# Okunrin Kan Ji Aguntan Gbe L, Ojo Oyingbe

EBUTE—METTA – Igbe ẹran aguntan kan ti obinrin alagba kan gbe wọ inu kotu adajọ awọn ọlọpa ni Yaba ni ọjọ Ru to koja ni o da iṣẹ duro fun igba diẹ ninu kotu awọn ọlọpa gẹgẹbi a ti gbọ nigbati ẹran na nke leralera.

( Wo yoku loju ewe kẹrin )


# Eleti-Ofe D'araba

# Ọkunrin to ji Aguntan

( O bẹrẹ loju ewe Ikẹta )

Aṣẹ ọkunrin kan ti nwọn npe ni Karimu Ayinde ni Ayinde ni o gbe aguntan ti nwọn gbe wọ inu kotu na lati fi han adajọ pe ohun ti o ji gbe ni, i aguntan yi fi ẹwọn oṣu mej la ko Karimu sinu ijọgọọn lati ọwọ adajọ Ọgbẹni Oye Ọyesanya.

Nigbati obinrin ẹlẹrau aguntan na ti orukọ rẹ njẹ Lambẹ Lawani njẹri ni kotu, o ni lati Ilọrin ni on ti ra aguntan na wa nigbati on si sọkalẹ ninu mọto ni Oyingbo ni Ebute Metta, on ba fi agun an na si itọju dẹrẹba mọto ti on ti nba bọ lati Ilọrin. O ni on lọ gba owo lara ọja fun awọn onimoto ni.

Obinrin na tun ni lẹhin ti on ti wọ ọja Oyingbo lọ tan lati ya ṣile meji lọwọ ọrẹ on kan lati fi ṣẹkun owo mọto ti on wọ, on ko ri aguntan on mọ nigbati on pada de lati sanwo fun dẹrẹba, ṣugbọn dẹrẹba wa dahun pe Karimu Ayinde ti san ṣile meji, o si ti gbe aguntan na lọ. Obinrin na ni ni on ba fi igbe ta.

Ni ipari ọrọ, Lambẹ Lawani to ni aguntan ni on ba gba tẹle Ayinde, on ba si te ni Opopo Griffith ni Ebute Metta pẹlu aguntan na lọwọ rẹ.

ẹṣẹ yi.

Agbẹjọro na fi han wipe ni igbati o ṣe wipe Ọgbẹni Leigh ni Ojogwu gba owo pọun mẹwa fun ako gbọdọ fi ẹsun na kan Ojogwu mo bi ki ṣe pe Ọgbẹni Leigh ni ao mu ẹsun rẹ wa iwaju Onidajọ, nitoripe Ojogwu jẹ iṣẹ ti Ọgbẹni Leigh ran ni.

Agbẹjọro na tun fi han Adajọ pe ti ko ba ṣe pe Ọgbẹni Leigh ni o ran lati gba owo na, gẹgẹbi 'ọga agba ko ba ti da ṣẹriya fun Ojogwu iti nṣe ọmọ abẹ rẹ.

A sun ẹjọ na si ọjọ kẹsan oṣu ti mbọ.

## Enia Meji Jona Ku Ninu Ija Igboro

MAIGBO – Enia meji ni a gbọ wipe nwọn jona ku ati pe awọn enia mejila miran tun ku pẹlu ninu ija igboro kan ti o ṣẹlẹ ni ilu Maigbo ni agbegbe ila orun.

A tun ri gbọ wipe awọn oṣiṣẹ Reluwe sa kuro ni ile iṣẹ wọn. Ogunlọgọ enia ni ọkunrin ati obinrin ati awọn ọmọ kekeke ni nwọn lọ sapamọ si inu ile kan ni siteṣọnu Maigbo. Awọn enia kan ti nwọn wa ibẹ pẹlu ibọn ti ina bọ ile na

Awọn enia bi ogun wa ni ile iwosan Oturkpo ati Makurdi fun itọju lọwọlọwọ yi. Nigbati awọn oniwe iroh n bere lọwọ awọn ọlọpa ni Makurdi awọn ọlọpa sọ pe awọn koi ti ri nkankan gbọ.

## Oruko Oga Olopa Moto Jade Ninu Esun Ponun Mewa

EKO - Ọga awọn ọlọpa Moto ni Ijọra ẹniti orukọ rẹ njẹ Ọgbẹni William Leigh ni orukọ rẹ jade ninu ẹsun owo ẹhin kan ti a mba ọlọpa kan ti orukọ rẹ njẹ Emmanuel Ojogwu ṣe,

Ojogwu ni ọlọpa kan ti a mu ẹsun rẹ wa si iwaju Adajọ pe ni ijọ kẹtala oṣu kẹrin ọdun yi, o gba pọun mẹwa owo ẹhin lọwọ o ni moto kan ti a npe ni Ganiyu Ọmọsanya, sugbọn Ojogwu ni on ko gba owo.

Nigbati agbẹjọro Ojogwu Ọgbẹni Alaso Aka-Bashce tun nwi awijare rẹ ni iwaju Adajọ, ni o fa orukọ Ọgbẹni Leigh jade. Agbẹjọro na fi han Adajọ pe ti o ba ṣe ni ododo ni Ojogwu gba pọun mẹwa o ni lati jẹ wipe o gba fun Ọgbẹni Leigh ni. Nitoripe Ojogwu pẹlu Ọgbẹni Leigh ni nwọn jọ wa ninu mọto kan ṣoṣo ni asiko ti o sọ pe Ojogwu daran

## Awọn Enia Lu Awọn Ti .. Fura Si Pe Nwọn Gbe Ọmọde

ACCRA- Irohin kan wa ku ni ọjọ kẹdọgbọn oṣu yi pe awọn ogunlogo enia lo lu awọn okunrin alaiṣẹ meji kan nipa fufura si nwọn pe gbe ọmọ gbe ọmọ ni nwọn.

A ri gbọ pe ifura yi bẹrẹ ni pa ẹrọ ina manamana ti a fe ri mọ inu ọgọdọ kan ni iha Akosombo ni Accra ọpọlọpọ irubọ ni a ti ṣe si inu ọgọdọ yi gẹgẹ bi pipa Adiye obuko ati malu nitoripe ki a le ri aye ko ile ẹrọ yi si ibẹ sugbọn pabo ni gbogbo rẹ nja si wọn ni afi ki nwọn fi odidi enia kan rubọ fun.

Okunrin kan ninu awọn ti wọn lu jẹ lebura i o si fa ọmọ rẹ ti nse ọmọ ọdun merin dani ni arin ilu ara fu awọn ara lu nigbati nwọn ri ọmọ kunrin na nwọn

(O oju ewe karun)

# NATIONAL BANK OF NIGERIA LIMITED

## Balance Sheet as at 30th JUNE, 1964

| 1963 £ | | £ | £ |
|---|---|---|---|
| | Capital | | |
| | Authorised: 3,250,000 Ordinary Shares of £1 each | 3,250,000 | |
| 3,180,539 | Issued and fully paid: 3,180,717 Shares of £1 each | | 3,180,717 |
| 3,813,935 | Current, Deposit and Other Accounts | | 4,396,876 |
| 1,000,000 | Loans and Advances from other Creditors | | 1,065,000 |
| 660,400 | Acceptances, Endorsements and Other Engagements on behalf of Customers per Contra | | 789,063 |
| £8,654,874 | | | £9,431,656 |

Note :
Profit for the year has been utilised in writing off bad Debts.

F. O. AWOSIKA, Chairman
S. L. DUROSARO, Managing Director
A. A. O. DUROSHOLA, Director
A. A. ADESIGBIN, Director

| 1963 £ | | | £ |
|---|---|---|---|
| 364,808 | Cash on Hand and Balances with the Central Bank of Nigeria | | 495,446 |
| 259,311 | Balances with and cheque in course of Collection on other Banks | | 75,629 |
| 430,000 | Money at Call and Short Notice | | 150,000 |
| 150,000 | Nigeria Government Tresury Bills | | 410,000 |
| | Investments at cost:– | | |
| 29,002 | British Government Securities (Market Value £30,923) | 29,002 | |
| 109,980 | Others (including Subsidiary Companies) | 107,480 | 136,482 |
| | Loans and Advances to costomers and other Accounts (including Subsidiary Companies) | 6,753,132 | |
| 5,670,922 | less Bad Debts written off | 49,776 | 6,703,356 |
| 980,451 | Bank Premises, Fixtures & Motor Vehicles at Cost less Depreciation | | 671,680 |
| 660,400 | Liabilities of Customers for Acceptances, Endorsements and other Engagements per Contra | | 789,063 |
| £8,654,874 | | | £9,431,656 |

A. ADEYINKA, Director
A. O. OSHINIBI, Director
A. A. LADEINDE, Director
T. A. ONIGBANJO, Senior Accountant

## AUDITOR'S REPORTS

We have obtained all the information and explanations which to the best of our knowledge and belief were necessary for the purpose of our audit. In our opinion, proper books of account have been kept by the Bank so far as appears from our examination of those books, and proper returns adequate for the purpose of our audit have been received from the Branches. We have examined the above Balance Sheet which is in agreement with the books of account and Returns of the Bank. In our opinion, and to the best of our information and according to the explanations given us, the said Balance Sheet is properly drawn up so as to exhibit a true and fair view of the state of the affairs of the Bank at the 30th June, 1964.

Dated at Lagos this 5th day of October, 1964.

OLATUNDE AYOOLA & CO. )
Chartered Accountants )
THOMAS, SILVA, DAWODU & CO. ) AUDITORS
Certified Accountants

## PROFIT AND LOSS ACCOUNT FOR THE YEAR ENDED 30th JUNE, 1964

| 1963 £ | | |
|---|---|---|
| 1,240,877 | Bad Debts written off | 49,776 |
| 76,618 | Losses and other charges written off | — |
| — | Balance unappropriated – 30th June, 1964 | — |
| £1,317,495 | | £49,776 |

| 1963 £ | | |
|---|---|---|
| 872,129 | Net Profit for the Year | 49,776 |
| 442,299 | General Reserves and Provisions brought from previous years | — |
| 3,067 | Balance Unappropriated – 30th June, 1963 | — |
| £1,317,495 | | £49,776 |

# Awon Arufin Şa Kuro Ni Itimole L'Aba

(O bẹrọ loju ewe keji)

Nwọn ni ija nla yi bẹ silẹ nigbati awọn enia mẹfa ninu awọn ara ileto na kọ lati san owo ori losi awọn ọ ọ a ti nwọn si ko wọn lọ si kotu ibilẹ to wa nibẹ, şugbọn ki awọn to ko awọn de kotu akọwe kotu şiwọ işẹ fun ọjọ na n pa bayi awọn ọlọpa ba ti gbogbo wọn mọle

Ko pẹ lẹhin eyi, awọn ibatan awọn enia ti nwọn ti mọle ba ya wọ inu kotu pẹlu ibinu, nwọn si bi awọn ọlọpa pe ki nwọn da wọn si e şugbọn akọwe kotu kọ jale lati fọwọ si iwe iduro wọn o wa şofun wọn pe ki nwọn pada wa ni ọjọ keji.

Ọrọ na bi awọn ara abule na ninu pupọ nwọn nwọn ba gbogun ti ile itimọle na nibibi nwọn gbe ti awọn enia mẹfa na mọ nwọn si jọ gbogbo wọn jade.

Nikẹhin ọga awọn ọlọpa kan, Ọgbẹni E yi pẹlu awọn ọlọpa miran lọ be ibi ti nkan yi gbe şẹlẹ wo, nwọn si wa ri enia meje nlu fun ibere ọrọ lori ija ma yi, şugbọn awọn mẹdogun to salọ ni nwọn şi nwa kakiri.

# Omo Olomo

(O bẹrẹ loju ewe kiuni)

Nigbati ọba ilu na ri wipe okiki rẹ nşẹ ga ju ti on lọ o bẹrẹ si binu si ko si şe dede pẹlu rẹ mọ ati pe abuku ati ẹtẹ ni ọba na nfi kan ninu ijoko ipade awọn ojoye ilu, oloye yi ko kọ ibi ara si, o şe bi owe; Adaba ko ni na ni a nkun igbẹ papa njo ẹiyẹ nlọ

Nigbati o di ọjọ kan ọba bere lọwọ rẹ eşe ti o jẹ wipe iwọn kan ni o da aşo si ninu gbogbo awọn ijoye ilu kini pataki nkan ti o ri ti o fi dawon si on yio pẹ şẹ pe ki o fa awọn mẹta danu kuro lori rẹ.

On fa ida yọ ki o si kibọ ni ehin on.

Ọba gba bayi fun oloye na nitori pe iku rẹ, gan ni ọba nwa nitori okiki rẹ ti o tan ka origun mẹrẹrin ijọba ilu na. Ọba ni ti o ba ya on yio ke si,

Oloye yi dọbalẹ o ta ika po po po o si şe Kabiyesi ọba alaşẹ ekeji o şa Dajudaju awọn aşọ mẹta nwọnyi ko dede de ori mi. Nitorina nko binu si ọrọ ti ọba sọ şugbọn e yi ti mo fẹ ni wipe ki ọba mọ itumọ awọn oşu mẹta na. Ti ọba ba mọ, ki o ti oju

Ọba bẹrẹ si wa idi ati itumọ awọn oşu mẹtta yi larin awọn oloye ilu ti nwọn jẹ wọ'e wọde Oloye yi şugbọn ko si ẹniti o le mọ itumọ rẹ ninu awọn, bẹ si ni ko si ẹniti o le da oju ko oloy na lati tete awọn nkan wọn yi n ọwọ rẹ.

(Koitu Pari)

## Arikogbon Ede Owe Ni Ede Oyinbo Ati Yoruba

1 Offer real help to aman when he is down and he never forget it
1 Şe ranlọwọ ododo fun ọkunrin ti o ba şubu ki yio gbagbe lailai
2 Think all you speak; but speak not all you think
2 Ro gbogbo nkan ti on sọ şugbọn ma şe sọ gbogbo nkan ti o ba ro.
3 A hen can sit still and earn a living but a man can't
3 Agbebọ adiẹ le joko ni ile ki o ri onjẹ, şugbọn ọmọ enia ko le joko nle ri onjẹ
4 sleep over it or you may weep over it.
4 Jẹ ki ibanujẹ okan rẹ ba orun lọ bi bẹkọ yio pọ ni ẹkun.
5 Many recieve advice only the wise profit by it.
5 Ọpọlọpọ ni a fun ni imọran Ọlọgbọn nikan ni o njẹ ere rẹ
6 The tide turns at low water as well as at high.
6 Bi igbi ti nja ninu ọsa ni o nja ninu iyọ.

## Pagidari Omo Odun Mesan Ni Oyun

PERU - Irohin kan wa pe ọmọ obinrin kan ti nşe ọmọ ọdun mẹsan npa ẹmọ ati bi ọmọ ni iha Gusu Lima ni ilu Peru.

A gbọ wipe awọn ọlọpa ti mu baba ọmọ na ẹ iti işe ọmọ ọdun merindinladọta, işẹ rẹ si jẹ a yan tu ẹdi.

Ni ọdun karun sẹhin iru nkan ba yi şẹlẹ ni ilu Peru ti ọmọbinrin kan ti orukọ rẹ njẹ Lina Medina ni oyun nigbati o di ọmọ ọdun marun ati oşu meje ti adahunşe şe işẹ ọbẹ ki a to le gbe ọmọkunrin iade ninu rẹ.

E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin

Eleti — Ofe

ti o kun fun irohin aladun losose

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28,Kosoko Street Phone 23370 Editor, (Olotu) Ola Quatade 15,Kosoko Street, Lagos, P O 467 Lagos,